# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI UBOGBO LAWA

No. 723 FRIDAY, JUNE 19, 1964 (2D)


## Obinrin Kan Lu Ọmọ Rẹ Pa!

TELAVIV:- Adajọ Ile ẹjọ gigu ti ṣe idajọ pe ki ọdaran Iyawo Ile kan, Iyaafin Gizelle Kafri, ẹni ọdun mẹrinlelogbọn o lọ si ẹwọn ọdun kan nitoripe o jẹbi ẹsun apania ti awọn Ọlọpa mu wa sile ẹjọ fun ni ọjọ Iṣegun ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi.

Abanirojọ Ijọba ti o ba ọdaran Iyawo Ile na ṣẹjọ ṣe alaye fun Ile-ẹjọ pe Iyawo Ile na bi ọmọkunrin kan, nigbati o si ṣe akiyesi pe ọmọ ko le sọrọ, o si tun ya odi ko le gbọran ni o ba binu lu ọmọ na pa patapata pe, "nitotọ ni mo ntọrọ ọmọ ti mo si fẹ bimọ, ṣugbọn ki iṣe iru ọmọ yi ni mo ntọrọ lọdọ Ọlọrun"

Nigbati awọn adajọ mẹtẹta ti nwọn wa nile ẹjọ na yadi, ti nwọn si ri daju pe nitotọ ni Iyawo ile na pa ọmọ rẹ nitori pe ọmọ na ko gbọran o tun jẹ odi ni nwọn ba ni ki o lọ si ẹwọn ọdun kan.

Ṣugbọn agbẹjọro Iyawo Ile na sọ pe ẹjọ ti nwọn da fun obinrin ko tẹ lọrun, awọn adajọ si fi obinrin na silẹ lori onigbọwọ, nwọn si ti kesi Olori Ijọba ilu wọn lati gba ọrọ na yẹwo, ṣugbọn a gbọ wipe o di oṣu kọkanla ọdun yi ki olori Ijọba wọn to sọrọ lori ẹjọ obinrin na. Bi nwọn ba ti pari rẹ si, ẹ maa gbọ o.

# IJỌBA FẸ ṢE IDAJỌ ẸJỌ OLOYE AWOLỌWỌ

EKO:- A ti bẹrẹsi gbọ hunnu-hunnu labẹlẹ kakiri igboro ilu Eko pe, Ile ẹjọ gigajulọ fun orilẹede Naijiria ti pari idajọ ẹjọ Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ olori ẹgbẹ Afẹnifẹre ati awọn mọkanla miran pẹlu re ti Apapọ Ijọba mba ṣẹjọ iditẹ ati ifi ipa ko ohun ọṣẹ wọlu.



Ọgbẹni Jakande

Gẹgẹbi irohin ti oni we irohin wa Ejon'-gboro ti o nfi imu finlẹ kakiri ile ẹjọ ati Teṣan awọn Ọlọpa fi ye wa ni ọsan ana, a gbọ wipe, awọn adajọ mararun ti nwọn gbọ ẹjọ kotẹmilọrun ti Oloye Awolọwọ pe sinu ile ẹjọ wọn ti pari akọsilẹ ẹjọ wọn tan patapata.

Irohin fi ye wa pe, awọn oṣiṣẹ ti o da iṣẹ silẹ, ni ko jẹki awọn adajọ na ti ṣe idajọ na.

Nitoripe, gbogbo awọn ọlọpa ni nwọn ṣiṣẹ-aṣeju ni gbogbo nkan bi oṣẹ meji ti awọn oṣiṣẹ fi binu da iṣẹ silẹ.

Atipe, diẹ ninu awọn ọlọpa na ti nwọn tun ba Dokita Michael Okpara lọ si irinajo rẹ ti o ṣe lọ si Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria laipẹyi.

A gbọ wipe awọn Ọlọpa ṣe iṣẹ gidigidi ni gbogbo asiko mejeji wẹnyi, Ijọba si fẹ ki nwọn sinmi bi ọṣẹ kan.

A gbọ wipe awọn Ọlọpa nilati ṣa gbogbo agbara wọn ni ọjọ idajọ na, ki nwọn si ri i daju pe, ẹnikẹni ko ja larin ilu. Ṣugbọn Ijọba fẹ ki awọn Ọlọpa sinmi diẹ ki ọjọ na to de; ni nwọn fi tun sun ọjọ ẹjọ na siwaju di ọjọ iwaju.

Ṣugbọn ni deede agogo mẹfa kutukutu awurọ ana, ni awọn ọlọpa bẹrẹsi kiri kakiri ninu mọto nla mẹrin ti nwọn si mura ogun ti nwọn si npoyi ọgba ẹwọn ni Broad Street ati Campbell Street titi de "Lion Buildings"

Nigbati awọn enia ti ri mọto awọn ọlọpa na larọ, ni nwọn ti lero pe ni owurọ ana ni Ijọba fẹ ṣe ẹjọ Oloye



**Oloye Ọbafẹmi Awolowo**
Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

Awolọwọ.

Lẹsẹkẹsẹ ni oniwe irohin wa ti mura ti o si lọ si Ile ẹjọ na ki o le ba ri aye joko ṣugbọn nigbati o de inu ile ẹjọ na, nwọn ṣe ẹjọ ṣugbọn ki iṣe ti oloye Awolọwọ.

Nigbati nwọn pari ile ẹjọ na lana ni oniwe irohin wa walọ bere lọdọ awọn alaṣẹ Ile ẹjọ na ọjọ ti nwọn fẹ ṣe ẹjọ Awolọwọ ṣugbọn ọkurin na sọ pe on ko le sọ.

Irohin kan ti a gbọ lati ọdọ awọn kan nilu ile iṣẹ na fi ye wa pe. Awọn Adajọ ti pari ẹjọ na tan patapata ṣugbọn awọn ko ti le sọ pe ọjọ kan ni nwọn o ṣe ẹjọ na.

Awọn alaṣẹ Ile ẹjọ na wa ṣe alaye pe, bọya ninu ọṣẹ yi tabi ọṣẹ ti mbọ ni nwọn o ṣe ẹjọ na.

A fun gbọ wipe ni ọjọ kọkandinlogun oṣu yi tabi ọjọ kẹdogbọn oṣu yi ni.

Awọn enia na tun fi ye wa wipe ẹjọ na ko le ju ọṣẹ ti mbọ yi lọ bi o ti wu ki o ti le ri.



Ọgbẹni Omisade



Ọlọla Adẹ Ademola

Irohin fi ye wa pe, awọn ọlọpa ti ngmura sile fun ẹjọ na ti o fi jẹ wipe ko ni si ija tabi rogbodiyan arin ilu



Ọgbẹni Onitiri

A gbọ wipe iṣẹ yio pọju fun awọn Ọlọpa larin ilu ni ọjọ na ti o fi jẹ wipe ko ni si isimi fun wọn, ṣugbọn a ko ti ri gbọ ohunti yio jẹ abayọri ẹjọ na ti imurasilẹ awọn Ọlọpa fi to bayi

Ṣugbọn irohin fi ye wa pe, gbogbo awọn ara ilu ni ọmọde ati ni

WO OJU EWE KẸFA

# AKẸJU NI BA ỌMỌ RERE JẸ

Lati Ọwọ BỌSẸDE SHOYINKA
Ansar-U-Deen School Itirẹ

Ẹ ku owurọ o, ẹnyin akẹkọ ẹlẹgbẹ mi. mo ti ṣe ileri lai pẹ yi pe ngo ma fi itan akọnilẹkọ da yin lara ya, Inu mi si dun pe olotu ko pe mi ni ọmọde ki o to gba mi layo lati maa sọ itan na. Mo si bẹ yin gidigidi pe ki ẹ farabalẹ ka itan mi na dada, ki ẹ si fi ọrọ inu rẹ kọ ẹkọ ti oye koroko.

## Olufẹ Mi Fẹ Tan Mi Jẹ

Mo jẹ Ọmọ ọdun mẹrindinlogun ti mo si nfẹ Ọmọdekunrin ti ọjọ ori rẹ to ọdun mẹtalelogun, mo ni ifẹ Ọmọkunrin yi pupọ, ti mo fi pinnu pe bo ba ṣe orun ma ba lọ sugbọn nigbati o ṣe ni ọjọ kan babalowo kan sọ fun mi pe Ọmọdekunrin yi ko ni fẹ mi o kan ntan mi lasan ni, Laipe emi na la ala nipa ọmọ yi nigbati nwon si tumọ ala na fun mi nwọn ni olufẹ mi ko ni fẹ mi wọle gẹgẹbi mo ti lero sugbọn nigbati mo sọ gbogbo ọrọ yi fun olufẹ mi na, o wipe irọ ni wọn pa, ala na si nda ẹru ba mi pupọ Njẹ Anti Ayọka, lero pe o yẹ ki kọ Ọkunrin na sile, ki si tete wa elomiran fẹ Tabi kini o yẹ ki nse

Boṣede Ogunuiyi

Suru-lere

IDANUN:— Nko lero pe ki o fi Okunrin yi silẹ ni wọn igbati o ti ṣẹ jalẹ pe irọ ni nwọn npa, Iwọ ni on yio gbe niyawo bi Ọlọrun k. ba kọ fun ẹru rẹ ko si ohun ti ọ kan ọ lati gbọọ ohun ti Babalowo yi wi ọrọ Babalowo yi ni o mu ọ lọkan ti o fi nla ala buruku yi, gbabe ọrọ Babalowo ati ala rẹ yi, ki o si ma fẹ olufẹ rẹ yi lo kosi ewu lagbẹrun ẹkọ aifi aidun Ọbẹ.

## Ọkọ Mi Ba Ọrẹ Imulẹ Mi Lopọ

Ni ọjọ kan nigbati ara ọkọ mi ko ya, mo ọl ki nile rẹ emi pẹlu ọrẹ-Imulẹ mi si ni a jijọ lọ. nigbati ọkọ mi si ni alafia mo tun lọ ki, si iyalẹnu mi mo ba on pẹlu ọrẹ Imulẹ mi yi lori ibusun, Loju mi ni ọkọ mi yi si bẹrẹsi fi mi rẹrin, ṣugbọn ọrẹ mi yi sare fi aṣọ ibusun bo oju, ki le ma ba ri, Mo joko fun iṣẹju melo, nigbati o ya mo dide mo lọ si ile.

Lati igbana emi ko ri ọkọ mi yi on na ko si bikita ati wa wo mi, .ọwọ majẹki purọ fun Ọ Anti Ayọka ọkan mi yi wa ni ọdọ ọkọ mi yi bi o tilẹ jẹ pe ọrẹ-Imulẹ mi yi fẹ gba ni ọwọ mi, Kini ki iṣe.

ABẸOKUTA, FELIC A ADEWALE

IDAMUN:— Ọkọ rẹ ati ọrẹ imulẹ yi ti fi iwa wọn han bi ẹni ti ko ṣe gbe ọkan le ati ọdalẹ enia. nitori na imọran mi si ọ ni pe ki o fi ọkunrin yi silẹ, ki o wa laju silẹ fun olotitọ olufẹ miran.

## Tea Pupọ Ko Dara.

Anti Ayọka, Inu mi dun pupọ lati kọwe yi siọ, ohun ti o iyọ mi lẹnu ti o mu mi kọ iwe yi si ọ niyi:- Igbagbogbo ni Baba mi ma nṣe kilọkilọ fun mi pe kio ye ma mu ti i ni ojojumọ mọ, nitori yio tete ba nkan ọmọ kunrin mi jẹ, bi ba dagba, Inu mi yio dun ti o ba le fun mi ni imọran nipa rẹ.

IBADAN Vesper Eashy

IDAHUN:— Emi ko tj gbọ eyi ri, gẹgẹbi m o t i m ọ tii jẹ onjẹ ti o dara, ti ko si ni ipalara, ti gbogbo agba-iyẹ si nmu, ṣugbọn o le jẹ pe o ma nfi ṣuga pupọ sinu rẹ ni o jẹki Baba rẹ sọ eyi nitorina ti o ba ri bẹ, ki iwọ papa ṣora nipa ọpọ ṣuga ninu tii rẹ n tori jẹdi jẹdi ni ṣuga ufa fun enia, Arun yi a si ma tete p.i nkan ọmọ kunrir ioto, ẹ o si di ọwọ rẹ.

Ẹ tun bọ ma fi ibere yin ranṣẹ si Anti Ayọka, ẹ jọwọ ẹ ma ma kọ, awọn ibere yin ua ki o ma han dada.

Itan mi na bẹrẹ bayi pe, Ni igba lailai baba ati iya kan wa ni ilu Eko kanna yi mo fi orukọ bo wọn ni asiri, Nwọn bi ọmọkunrin kan ṣoṣo ni ọjọ aiye wọn, nwọn si jẹ ọlọrọ, eyi mu ki nwọn tọ ọmọ kanṣoṣo ti nwọn bi na bajẹ,

Nwọn fi ọmọ na si ilewe eyiti iba 'fi lọ si ilewe deede ni ṣe ni a ama kakiri ilu asi



BỌSẸDE SHOYINKA

maa ba awọn ọmọ alailẹkọ bi tirẹ ju ọkuta kakiri arin ilu. Bi alukọni ba si wa fi ẹjọ rẹ sun ni ile pe ko wa si ile ẹkọ, eyiti awọn obirin rẹ iba fi panupọ bẹa wi, nse ni nwọn tubọ ngọọ sii nipa sisọ bayi pe "ohun ti Ọlọ—run ba fun enia ni gba ao sa ni lu pa, kii se ọran iyan lati kowe ẹniti ko mọ iwe sa nkọle mọ ile nwọn sa nkan asẹ mọ aṣẹ"

Ọrọ ti o ngbọ lẹnu awọn obi rẹ yi tubọ mu ki o ma ṣọṣin ṣora ninu iwa bajẹ, Lẹhin ọdun j ọ jọ awọn ẹlẹgbẹ rẹ jade ile iwe, nwọn bẹrẹ si ṣe iṣẹ, Ni kukuru olukuluku wọn wulo fun obi wọn ati ilu wọn pẹlu, Ṣugbọn ọmọ ti mo nwi yi ko mọ,

A yatọ si Bi sibẹsibẹ nri owo iya rẹ ati baba rẹ na ni inakuna,

Ogbo de lọrọ kan, baba rẹ ku, edi ẹdun kẹta iya rẹ tẹle, Ogun baba ati iya rẹ si wa ni ikawọ rẹ

Owa ngna owo yala i a ti fẹ, nigbati oya ni oba wọ ẹgbẹ ọmuti ni nwọn ba sọ ni "A R O W O I Y A BUNA, AROWO BABA DABIRI"

Ko jẹ ki orukọ yi gba Ọdun kan lẹhin iku awọn obi rẹ ti o fi ta tile tọna mu ọti tan.

Iṣẹ wa wọ ni ewu, osi wa da ṣokoto peupe si ni idi, o wa di atọrọje awọn ọrẹ rẹ ọjọ kini ti won jijo ngmuti amuudat o wa bẹrẹsi yẹra fun un

Ọmọ oninakun ji nu sigar ju reluwe lo ni gbati aiye rẹ lai ti ku.

Ni Ọjo kan nigbati orugbe siga ngbe ẹ ni o ba rapala wo ile itaja kan ni adugbo kan ni Eko ti nwon npe ni Offin, ni o ba ji agolo siga kan gbe.

Awọn baba wa ni i maa pa lowe pe, "Ọjọ gbogbo ni ti ole, ọjọ kan ni ti oninkau" ọwọ ṣẹkun tẹẹ, ni nwọn ba bẹrẹsi pa ni ẹti agbay dande ki nwọn to fa

"O OJU EWE KARUN

## Iwọ Ha Fẹ Kọ Ile Bi ?

Bi o ba fẹ ra ilẹ tabi o fẹ ta ilẹ tabi boya o fẹ kọ ile.

Tete kọwe si wa fun gbogbo awọn ohun ti o ba nfẹ.

Bi o ba kọ ile, a le ma a ba ọ gba owo lọwọ awọn olugbe ile rẹ kia kia, ki owo na o si tẹ ọ lọwọ ni asiko.

Tabi ti enia ba je o lowo ti ko san, kọwe si wa, were ni a o ba ogba a lowọ rẹ

Fun ẹkunrẹrẹ alaye, kọwe siwa. ki o si dan wa wo lẹ ẹ kan ṣo ṣo a o si fi ohun gbogbo tẹ ọ lọrun

J.O. Shoyinka.
General Manager
1, Ishiba Street
Itirẹ—Yaba

# Gomina Ba Igbimọ Ijọba Ibilẹ Ikorodu Sọrọ

IKORODU:- Gomina Ipinlẹ Iwọ orun Naijiria Ọlọla Odẹleyẹ Fadahunsi rọ gbogbo enia Ipinlẹ Iwọ Orun lati se iṣe wọn pẹlu olitọ lati le ran Ijọba Ipinlẹ na lọwọ fun eto idagbasike ti Ipinlẹ na.

Ọlọla Odẹlẹyẹ si nsọ ọrọ yi nigbati o nfi esi si iwe ẹyẹ Ikini ku abọ ti awọn Igbimọ ibile ti ilu Ikorodu ṣe fun lasiko irin ajo rẹ si agbegbe na.

Ọlọla Odẹleyẹ si tun rọ awọn enia na leti ṣe iṣe wọn pẹlu ifẹ ati ododo ki awọn enia le ni igbẹkẹle ninu nwọn.

Ọlọla Odẹleyẹ si tun sọ fun awọn Igbimọ na lati ni ẹmi isowọpọ Igbimọ pẹlu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria eyiti iṣẹ wọn si jẹ lati le ri pe eto alafia si wa pẹlu awọn enia kakiri agbegbe ni Ipinlẹ na.

Gomina na si tun fi ye awọn Igbimọ na fun iye owo tabua ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ya silẹ lati na fun agbegbe wọn ti iye rẹ si jẹ (£50,000) lati fi ṣe ẹrọ omi, Ọlọla Odẹlẹyẹ si tun sọ fun awọn enia na pe Ikorodu yio gba ipin ti nwọn ninu awọn ti Ijọba Ipinlẹ na ya silẹ fun nwọn Ninu iwe ẹyẹ ikini ku abọ ti awọn igbimọ na fun Gomina na, nwọn si sọ sinu iwe na pe awọn nfẹ ki Ijọba Ipinlẹ na lati fun nwọn ni awọn ohun elo gegebi onti ẹrọ lati yọ ọda si awọn ọna nwọn ti o ku lati fun wọn ni ọga agba fun eto ilera ni ilu Ikorodu.

Gomina na si se ileri fun wọn pe on yio ṣe gbogbo ohun ti nwọn bere fun awọn oludari iṣẹ na.

Ọpọlọpọ awọn enia lo si wa pade Gomina na ninu wọn ni awọn ọmọ ile ẹkọ, awọn olorin Ọlọja ati awọn enia jankajakan ninu wọn ni Alakoso eto irohin Ijọba apapọ oloye T.O.S. Benson.

# YE IRAWỌ RE WO

AQUARIUS (Jan 20 - Feq 18) Ohun kan ti o ṣẹṣẹ fẹ bẹrẹ yio dara, ṣugbọn kọkọ ṣe akiyesi ara rẹ na, ṣọra nipa iṣẹ kan ti o fẹ ṣe, ipade iwọ pẹlu ọrẹ rẹ kan yio larinrin.

PISCES (Feb 19 - Mar 20) Ire ni ọjọ oni jẹ fun ọ, ṣiṣe ti ki o ṣe gbogbo iṣẹ rẹ ma ṣalaiṣe ọkan. Ohun ti o nro lọkan rẹ dara.

ARIES (Mar 21 - April 19) Iwe kan ti o pẹ ki o to de, maṣe gbe ara le nitori pe, ohun ti o nfẹ ko si nibẹ. Ija kekere kan yio bẹ silẹ larin iwọ pẹlu ẹbi rẹ ati ẹnikan ti o fẹran.

TAURUS (April 20 Mar 20) Ire ni ọjọ oni, ṣe suru, ki o fa ẹnikan ti iwọ korira mọra, toripe ajumọṣe rẹ pẹlu rẹ, yio ṣe anfani, rin faaji lọ si ode, ire mbẹ fun ọ.

GEMINI (May 21 - June 21) Maṣe gbọn pupọ ju, ki o ṣe suru o yẹ ki o ni ọgbọn wẹwẹ, masi ṣe tọrọ ohun kan, iwọ yio ba ọrẹ titun pade loni.

CANCER (June 22 - July 22) Ire yio pọ ninu ohun kan ti o ti bẹrẹ, maṣe gbagbe ara rẹ rara, Ire ni ọrọ ifẹ yio jẹ si ọ loni.

LEO (July 23 Aug 22) Irin ajo mbẹ fun ọ, ṣugbọn ṣọra nitori ewu mbẹ fun ọ ni irin ajo rẹ na, maṣe fi awọn ẹbi rẹ ṣere, da ohun ti o ya pada, maṣiṣe jeki inure rẹ papọju si awọn ẹniti iwọ kọ mọ.

VIRGO (Aug 23 - Sept 22) Ọjọ alanu ni oni jẹ fun ọ ki o ma si ṣe ba ikan jẹ, idalẹ kan ti ofẹ lọ yio fun ọ ni gbogbo nkan ti o fẹ, iwọ yio ba obinrin ṣere ako, iwọ yio si lọ si ipade ti faaji loni.

LIBRA (Sept 23—Oct ) Ṣe jeje ki o si tọju ọgbọn ori rẹ, lọ fi ara lele ki o simi, ki o ma ba ri asasi ti o nlẹ yọ ọ lẹnu yi.

SCORPIO (Oct. 24—Nov. 22) Gbogbo enia yio ma gbadun rẹ lọjọ oni, idarasa yio si wa fun ọ.

SAGITTARIUS (Nov. 23 Dec. 21) Loni gbogbo nkan ni yio su ọ, ṣugbọn iwọ yio pẹẹdẹ ni pipari ọrọ ọwọ kan ti ombẹ nile.

CAPRICORN (Dec 22- Jan 19) Ọjọ ibinu li oni, ohun ti ẹtọ ni ki osi ma se ọrọ nipa ifẹ ni ki oma sọ loni, ma wo inu awọn iwe irohin gbogbo ma si se fi ọkọkan ṣofo

BI O BA NI

Iwe—Titẹ

FUN

Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku

ATI

Iwe Igbeyawo

TETE KỌWE SI ILE—IṢE—ERỌ ITẸWE

Modupẹ Printing Press

16 Bamgbose Street, P. O. Box 1495

Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ERỌ ITẸWE WA NHAN

OWO POKU NI A SI NGBA

IROHIN KO TO AFOJUBA

Dan wa we Iẹyẹkorọsọ ko ri iyato

hannjẹ Tabi Irena Rẹ de Opin Ayọ De

Ojulowo Egbogi awọn Faranse gidi ti a npe ni

'CORSIVER'S



Ojulowo ati Ajẹbidan Atamatase Egbogi ti a ṣe ni pataki Fun „ARỌN KINIŞA" tabi LATANATAN'i ti o ma mu idiwọ wa fun Obinrin lati Fẹra u tabi lati ma ṣe abiyamọ meji rẹ kosi kakiri igboro ilu Eko. Lẹhin ti o ba ti lo egbogi awọn yi tan ti inu-riru, aya ririn, ẹhin didun tabi aikoto ẹjẹ lara, ẹjẹ dudu ibadi gige ... ba nyọ ọ lẹnu, ibẹsibẹ bere ojulowo egbogi ti awọn Oyinbo ṣe nipataki fun AJO "OBINRIN" ti awọn anodi wọnyi ba nyọ lẹnu ti wọn npe ni egbogi ... ẹjẹ ni ṣọbu awọn

NIGERIAN MEDICINE STORES

Tinubu Square Lagos

Waterloo Stores

8, Palm Church Street, Lagos,

Phone:- 2287 Nigeria. (Ọja Ita Faji Lagos.)

ADEDUN CHEMIST

14. Wakeman Street Lagos

ATI NI AWỌN ŞOBU IBADAN:—

IŞẸ LODUNMARE DISPENSARY OKE-BỌLA

E ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ Ki ẹ si maa Polowo Ọja Nyin Sinu Rẹ Pẹlu

# Gomina Ba Igbimo Ijoba Ibilę Ikorodu Sorọ

IKORODU:- Gomina Ipinlę Iwọ orun Naijiria Olọla Odeleye Fadahunsi rọ gbogbo enia Ipinlę Iwọ Orun lati se işe wọn pelu olitọ lati le ran Ijọba Ipinlę na lọwọ fun eto idagbasike ti Ipinlę na.

Ọlọla Odęlęyę si nsọ ọrọ yi nigbati o nfi esi si iwe ęyę Ikini ku abọ ti awọn Igbimọ ibile ti ilu Ikorodu şe fun lasiko irin ajo rę si agbegbe na.

Olọla Odęleyę si tun rọ awọn enia na leti şe işe wọn pelu ifę ati ododo ki awọn enia le ni igbękele ninu nwọn.

Olọla Odęleyę si tun sọ fun awọn Igbimọ na lati ni ęmi isowọpọ Igbimọ pęlu Ijọba Ipinlę Iwọ Orun Naijiria eyiti işọ wọn si ję lati le ri pe eto alafia si wa pęlu awọn enia kakiri agbegbe ni Ipinlę na.

Gomina na si tun fi ye awọn Igbimọ na fun iye owo tabua ti Ijọba Ipinlę Iwọ Orun ya silę lati na fun agbegbe wọn ti iye rę si ję (£50,000) lati fi şe ęrọ omi, Olọla Odęlęyę si tun sọ fun awọn enia na pe Ikorodu yio gba ipin ti nwọn ninu awọn ti Ijọba Ipinlę na ya silę fun nwọn Ninu iwe ęyę ikini ku abọ ti awọn igbimọ na fun Gomina na, nwọn si sọ sinu iwe na pe awọn nfę ki Ijọba Ipinlę na lati fun nwọn ni awọn ohun elo gegebi onti ęrọ lati yọ ọda si awọn ọna nwọn ti o ku lati fun wọn ni ọga agba fun eto ilera ni ilu Ikorodu.

Gomina na si se ileri fun wọn pe on yio işę gbogbo ohun ti nwọn bere fun awọn oludari işę na.

Ọpọlọpọ awọn enia lo si wa pade Gomina na ninu wọn ni awọn ọmọ ile ękọ, awọn obirin Ọlọja ati awọn enia jankajankan ninu wọn ni Alakoso eto irohin Ijọba apapọ oloye T.O S Benson.

# YE IRAWỌ RE WO

AQUARIUS (Jan 20 - Feq 18) Ohun kan ti o şęşę fę bęrę yio dara, şugbọn kọkọ şe akiyesi ara rę na, şọra nipa işę kan ti o fę şe, ipade iwọ pęlu ọrę rę kan yio larinrin.

PISCES (Feb 19 - Mar 20) Ire ni ọjọ oni ję fun ọ, şişe ti ki o şe gbogbo işę rę ma şalaişe ękan. Ohun ti o nro lọkan rę dara.

ARIES (Mar 21 - April 19) Iwe kan ti o pę ki o to de, maşe gbe ara le nitori pe, ohun ti o nfę ko si nibę. Ija bękere kan yio bę silę larin iwọ pęlu ębi rę ati ęnikan ti o fęran.

TAURUS (April 20 Mar 20) Ire ni ọjọ oni, şe suru, ki o fa ęnikan ti iwọ korira mọra, toripe ajumọşe rę pęlu rę, yio şe anfani, rin faaji lọ si ode, ire mbę fun ọ

GEMINI (May 21 - June 21) Maşe gbọn pupọ ju, ki o şe suru o yę ki o ni ọgbon węwę, masi şe tọrọ ohun kan, iwọ yio ba ọrę titun pade loni.

CANCER (June 22 - July 22) Ire yio pọ ninu ohun kan ti o ti bęrę, maşe gbagbe ara rę rara, Ire ni ọrọ ifę yio ję si ọ loni.

LEO (July 23 Aug 22) Irin ajo mbę fun ọ, şugbọn şọra nitori ewu mbę fun ọ ni irin ajo rę na, maşe fi awọn ębi rę şere, da ohun ti o ya pada, maşişe jeki Inure rę papọju si awọn ęniti iwọ ko mọ.

VIRGO (Aug 23 - Sept 22) Ọjọ alanu ni oni je fun ọ ki o ma si şe ba ẹnikan ję, idalę kan ti o fę lọ yio fun ọ ni gbogbo nkan ti o fę, iwọ yio ba obinrin şere akọ, iwọ yio si lọ si ipade ti faaji loni.

LIBRA (Sept 23—Oct ) Şe jeje ki o si tọju ọgbọn ori rę, lọ fi ara lelę ki o simi, ki o ma ba ri asasi ti o nlę yọ ọ lęnu yi

SCORPIO (Oct 24—Nov. 22 ) Gbogbo enia yio ma gbadun rę lọjọ oni, idaraya yio si wa fun ọ.

SAGITTARIUS (Nov 23 Dec. 21) Loni gbogbo nkan ni yio su ọ, şugbọn iwọ yio peredę ni pipari ọrọ ọwọ kan ti ombę nile.

CAPRICORN (Dec 22- Jan 19) Ọjọ ibinu li oni, ohun ti otọ ni ki osi ma se ọrọ nipa ifę ni ki oma sọ loni, ma wo inu awọn iwe irohin gbogbo ma si se fi ọkọkan şofo

BI O BA NI

Iwe—Titę

FUN

Lilo nibi Işę rę tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku

ATI

Iwe Igbeyawo

TETE KỌWE SI ILE—IŞE—ERỌ ITĘWE

Modupę Printing Press
16 Bamgbose Street, P. O Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ERỌ ITEWE WA NHAN
OWO FOKI NI A SI NGBA
IROHIN KO TO AFOJUBA
Dan wa wo Iğkanjọşọ ko ri iyato

bannję Tabi Irona Rę de Opin Ayọ de

Ojulowo Egbogi awon Faranse gidi ti a npe ni

'CORSIVER'S



Ojulowo ati Ajębidan Atamatase Egbogi ti a şe ni pataki Fun „ARỌN KINIŞA" tabi LATANATAN'i ti o ma mu idiwọ wa fun Obinrin lati Fęra u tabi lati ma şe abiyamọ meji rę kosi kakiri igboro ilu Eko. Lęhin ti o ba i lo egbogi aron yi tan ti inu-riru, aya ririn, ęhin didun tabi aikoto ęję lara, ęję dudu ibadi gige ... sisun ba nyọ ọ lęnu ibęsibę here ojulowo egbogi ti awọn Oyinbo şe nipataki fun AJO "OBINRIN" ti awọn amodi wọnyi ba nyọ lęnu ti wọn npe ni egbogi ara ęję ni şọbu awọn

NIGERIAN MEDICINE STORES
Tinubu Square Lagos
Waterloo Stores
8, Palm Church Street, Lagos.
Phone:- 2287 Nigeria. (Ọja Ita Faji Lagos.)
ADEDUN CHEMIST
14. Wakeman Street Lagos
ATI NI AWỌN ŞOBU IBADAN;—
IŞẸ LODUNMARE DISPENSARY OKE-BỌLA

E ma a Ka Iwe Irohin Imolę Lojojumọ Ki ę si maa Polowo Ọja Nyin Sinu Rę Pęlu

# ỌTẸLẸMUYẸ NKINYIN O!

Ẹ ku ọjọ mẹta o, ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ, igbati a ba ri ni, ni owurọ ẹni, mo ki gbogbo yin pe, "A GUDU MỌNI SA" Ọlotu mo juba rẹ o, iba awọn alabaşişẹ rẹ pẹlu. Ki nto rekọja lọ si Ibadan ni ọjọ kini, mo şe ileri pe, ngo mu irohin ti o gbamuşe bọ lati Mesiọgọ ni ile Oluyọle nibiti ole gbe njare oni nkan, şugbọn rogbodiyan ti o nbẹ silẹ larin awọn oşelu ko jẹki nle raye bọ sihin, bọ sọhun

Eyi ko le jẹki ngmu irohin kan bọ, nko ni purọ tan yin jẹ ẹnyin onkawe mi, "Ogun nba ọmọ oojọ ja ni Ibadan" toto o şebi owe o. Nisisiyi mo tun ti wọ ilu de ki awọn ole, igara, Ọlọşa ati awọn ọmọ jaguda pẹlu awọn aşẹwo para mọ o.

Bi Oluwa ko ba kọ işẹ ẹru rẹ, ngo bẹ le awọn aşẹwo iyawo jaguda Mushin lẹhin.

Ngo si tuna asiri wọn bi nwọn ti şe jẹ "awunifọtin" ọkọ wọn Nko bẹru enia a fi Ọlọrun Ọba to da mi, gbogbo awọn oluşe buburu ni ngo fa si ọtun awọn ọlọpa porongodo.

Emi Ọtẹlẹmuyẹ
S'awo d'ele Ira
Mo gb'ọmọagodongbo
Mo kawo d'ele Iwo
Mo gba wundia
Ọlọmu gọgọgọgọ
Fi şe 'yawo.
Ẹda kii r'oşu
Ko ma yọ mọ
Bẹ si ni
Ẹyọ mọ mi
şẹşẹ l'ọmọde yọ
M'ẹiyẹ-şẹşẹ.
Nitoripe a gbe ni
Gbere pade Olokun
Aluko ni gbere
Pade ọlọsa
Odidẹrẹ ni
Gbere pade oburo
Aki fẹ didun ku
L'ape Oyin
Sinkinmini
Afaimọni konimọra
Ẹko mi mọra
Gbogbo aiye
Ẹ ko mi mọra
T ẹru T'ọmọ agbailu
Ẹ fa mi mọra
Ọba ilu
Ẹ ko mi mọra
Ijoye ilu
Ẹ ko mi mọra
Itun loni
kẹ tun mi se loni
Ifa loni kẹ
Fami mọra loni
Wari lo ni
kẹ f'owo l'ọmọ
Wa mi ri

Ire ile, ire oko ki ojẹ ti emi Ọtẹlẹmuyẹloni ati awọn onkawe irohin imọlẹ pẹlu Odigba kan na o

## Akẹju Ni Ba Ọmọ Rere Jẹ

LATI OJU EWE KEJI

le Ọlọpa lọwọ.

Ko ba ọrọ pẹ lọ titi ti o fi yẹwo ninu akọsilẹ rẹ lọdọ awọn Ọlopa pe jiji ni ou ji pangolo siga,

Ni Ọjo keji ti nwọn mura ni o farahan niwaju adajọ Ọrọ akoko ti adajo si.

Kọkọ bere lọwọ rẹ nigbati awọn adajọ fi ẹsun ole kan an tan ni pe, O jẹbi tabi on ko jẹbi atipe kini o ni sọ ki ngto şe idajọ fun ọ?

O si da adajọ lohun pe mo jẹbi ẹsun ole ti nwọn fi kan mi, şugbọn mo ni ọrọ kan sọ kiẹ to şe idajọ le mi lori.

Adajọ na si dalohun mo ngbọ ọrọ rẹ na.

AROWO IYA BUNA SỌRỌ

Arowo iya buna ni Kabiyesi; Lotitọ ni mo le jale, ki şe ẹjọ mi bikaşe awọn obi mi ti tọ mi ni itọkutọ nigbati mo wa ni kekere ti nko fi mọ buburu yatọsi rere, şugbọn nisisiyi ti mo dagba tan iwa ibajẹ ti di ba raku fun mi. Ti o ba şẹşẹ ki nwa ile aiye nigbamiran nko ni ya si ọdọ iru awọn obi bẹ ẹ mọ lailai nitoripẹ nwọn ti sọ aiye mi di ibajẹ, ohun ti ẹ ba fẹ ki ẹ şe fun mi mo faramọ".

Adajọ na wa yiju si awọn ti o wa ni kotu na o ni "Şe ko wa rii pe itọju ọmọ si ọna rere şe pataki atipe 'ati kekere ni ati npa ẹkan idi iroko ti o ba dagba ọwọ kii ka ni" ni ọrọ ti ọmọ arufin yi, ntọkutọ ti awọn obi rẹ tọ, ni o fi yayakuya laişeani ani awọn obi na ni o baa jẹ.

Nitori idi eyi mo da silẹ, ki o ma lọ ni alafia.

Mo si fi eyi fun leti, bọya o le wulo ni Ọjọ miran" Bayi ni itan mi na pari loni

Ẹnyin obi ni itan mi yi bawi, e ma a tọ Ọmọ yin si oju ọna ti Ọlọrun ati ọna ti o tọ, ki o ba le wulo fun yin, ara rẹ, ati ilu rẹ lẹhin Ọla.

Odigba kan na ao tun ma gburo ra wa ni ọjọ Abamẹta ti o mbọ lagbara Oluwa O.


TRADITION REFLECTED IN PROGRESS

DON'T FORGET THAT YOU CAN ALSO TRADE IN YOUR OLD MERCEDES-BENZ or RENAULT CAR!

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.

